# REVISTA NJINGA & SEPÉ

Revista Internacional De Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras



ISSN: 2764-1244

Vol. 5, Nº Especial I, 2025

Universidade da Integração Internacional da Lusofonia Afro-Brasileira
Sistema de Bibliotecas da Unilab
Catalogação de Publicação na Fonte

N659

Njinga & Sepé : Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras. - Ano 1, n. 1 (2021)- . - São Francisco do Conde, BA: Instituto de Humanidades e Letras dos Malês, Unilab, 2021- .
v.

Editor: Alexandre António Timbane.
Co-editores: Denise Silva, Ezra Alberto Chambal Nhampoca, Kelly Priscila Lóddo Cezar, Manuel da Silva Domingos e Maria Goreti Varela Freire Silva.
ISSN 2764-1244.

1. Linguagem e cultura - Periódicos. I. Timbane, Alexandre António (Ed.).

BA/UF/BSCM CDD 405

Ficha catalográfica elaborada por Bruno Batista dos Anjos, CRB-5/1693

## EQUIPE PRINCIPAL

### Editor-chefe

Alexandre António Timbane (Universidade de Integração Internacional da Lusofonia Afro-Brasileira, Brasil)

### Coeditores Permanentes

Denise Silva (Universidade Federal da Grande Dourados e Instituto de Pesquisa da Diversidade Intercultural, Brasil-Línguas e cultura indígenas brasileiras)

Ezra Alberto Chambal Nhampoca (Universidade Eduardo Mondlane, Moçambique-Cultura e Línguas bantu/Universidade Trás-os-Montes e Alto Douro, Portugal)

Kelly Priscila Lóddo Cezar (Universidade Federal do Paraná, Brasil- ´Cultura e Línguas de Sinais)

Manuel da Silva Domingos (Universidade Agostinho Neto, Angola-Línguas e culturas africanas)

Maria Goreti Varela Freire Silva (Universidade de Cabo Verde, Cabo Verde-Crioulos de base lexical portuguesa)

## EDITOR CONVIDADO/ GUEST EDITOR

**BAYỌ ỌMỌLỌLA**

**(Department of World Languages and International Studies Morgan State University, Baltimore, USA)**

## INSTITUIÇÃO

**Universidade de integração Internacional da Lusofonia Afro-Brasileira**

**Instituto de Humanidades e Letras- Campus dos Malês**

**Avenida Juvenal Eugenio de Queiroz, s/nº, Baixa Fria, CEP: 43900-000, São Francisco do Conde, Bahia, Brasil, E-mail: revista.njinga.sape@unilab.edu.br**

## REVISORES/AVALIADORES /REVIEWERS


**ABDOULAYE MBAYE (College of Liberal Arts Morgan State University, Baltimore, MD, USA)**

**ABDUL NANJI (Department of Middle Eastern, South Asia, and African Studies, Columbia University)**

**ABÍDÈMÍ BỌ́LÁRÌNWÁ (Department of Linguistics and African Languages University of Ibadan, Nigeria)**

**ABU-UBAIDA SANI (Department of Languages and Cultures, Federal University of Gusau, Nigeria)**

**ADEỌLA ADIJAT FALẸYẸ (Ọbafẹmi Awolowo University, Ile-Ifẹ, Nigeria)**

**BAYỌ ỌMỌLỌLA (Department of World Languages and International Studies Morgan State University, Baltimore, USA)**

**BENJAMIN KUNI (Department of B N Ghanaian, Languages and Linguistics, University of Cape Coast, Ghana)**

**CECILIA TOMEKYIN (University of Education, Winneba, Ghana)**

**CORNELIUS ONANUGA (Yoruba Department School of Language Sikiru Adetona College)**

**FRANCIS EHOMA KWAW (Ghana Bureau of Languages, Ghana)**

**FUNMILAYỌ ADESANYA-DAVIES (Faculty of Humanities, Ignatius Ajuru University of Education Rumuolumeni, Port Harcourt, Nigeria)**

**FÚNMILÁYỌ̀ TÈMÍTỌ́PẸ́ ÀJÀYÍ (Department of Yorùbá, Adéyẹmí Federal University of Education, Oǹdó, Nigeria)**

**GABRIEL AYOOLA (Department of Afro-American and African Studies (University of Michigan, Ann Arbor, Michigan)**

**IMU FAMOUS OGHOGHOPHIA (National Institute for Nigerian Languages, Aba, Nigeria)**

**ISSA UMAR AL-MUSAWI (Peacock College of Education, an Affiliate of Taraba State University, Jalingo, Nigeria)**

**JULIANA DANIEL (Ohio University, Athens, Ohio, USA)**

**KOFI AGYEKUM (Department of Linguistics University of Ghana, Legon, Ghana)**

**LUQMAN KIARIBẸẸ (Ọṣun State University, Ikire, Nigeria)**

**MALTIDA TETTEH (University of Education, Winneba, Ghana)**

**MATTHEW KỌLAWỌLE ONI (Department of Communication and Media Studies, Ajayi Crowther University, Ọ̀yọ́, Nigeria)**

**MOSES DARAH (Delta State University, Abraka, Nigeria)**

**MUSTAPHA HASHIM KURFI (Department of Sociology Bayero University, Nigeria)**
**ỌLÁLÉRÈ ADÉYẸMI (Department of Linguistics and Nigerian Languages, University of Ilọrin, Ilọrin, Nigeria)**
**ỌMỌLAYỌ D. OGUNLỌLA (Department of Lingustics and Nigerian Languages, University of Ilọrin, Nigeria)**
**PHILIPO LUBUA (Pittsburgh University, Pittsburgh)**
**RAHINATU IBRAHIM TAIBA (University of Education, Winneba, Ghana)**
**RAPHAEL A. ADESUYAN (Adeyẹmi Federal University of Education, Ondo, Nigeria)**
**RAYMOND AMOAKWA (University of Education, Winneba, Ghana)**
**ROSE AZIZA (Independent Researcher, Delta State, Nigeria)**
**TAIWO AKINDUTI (Ọṣun State University, Ìkirè, Nigeria)**
**TAOFIQ SA'ADU (Department of Yorùbá, Adéyẹmí Federal University of Education, Ondo, Nigeria)**
**UBA ALIYU, Lecturer, Department of Linguistics, Adeyemi Federal University of Education, Ondo, Nigeria**
**WAHABI ADEGBAYI (Tai Solarin Federal University of Education, Ijẹbu-Ode, Nigeria)**

**Design de imagens e capa**
Leonardo Fotchizes (UNILAB)
Alexandre Alejota Sapalo (UNILAB)
**Logotipo da Revista**
Anderson Nowogrodzki da Silva (UnB)

**African Journals Oline (AJOL):** https://www.ajol.info/index.php/njinga/about

Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras
São Francisco do Conde (BA) | vol. 5, nº Especial I | p. 07-10 | jan./ jun.2025.

# Ìfáárà: *Njinga & Sepé* Gbé Àkànṣe Yìí Jáde Lórí Lítíréṣọ̀ Alohùn Ìlẹ̀ Adúláwọ̀

**Guest Editor**
**Bayọ Ọmọlọla, Ph.D**
ORCID iD https://orcid.org/0009-0007-0650-7805

Ọ̀tọ̀lọ́rìn ni jọ́nà *Njinga & Sepé* ti sáà yìí. Kedere ló fi yàtọ̀ sí àwọn ẹ̀dà rẹ̀ tó ti jáde tẹ́lẹ̀ rí. Ní tòótọ́, àṣà Brazil àti tí Áfíríkà ló jẹ ìwé àtìgbàdégbà yìí lógún óòrèkóòrè, ṣùgbọ́n ní sáà yìí, ó fi síbì kan ju ibì kan lọ; odù Áfíríkà ló jáde gedegbe lójú ọpọ́n jọ́nà yìí. Ìdí nìyí tí ó fi fi odidi àtẹ̀jáde méjì jin lítíréṣọ̀ alohùn Adúláwọ̀.

Lítíréṣọ̀ alohùn Áfíríkà jẹ́ àkà ìtàn, ohun amáyétura, ọ̀nà ìgbara-ẹni kalẹ̀, ìfọgbọ́nsọ̀rọ̀, ìkìlọ̀, ìsìnilétí, ìfanimọ́ra, àti ìtinidànú. Ò pín sí orísìírísìí. Àwọn kan wà tó wọnú àwọn mìíràn. Jọ́nà tó jádé yìí kò jáde ní ọ̀bọrọgidi.

Ẹ̀là lọ̀rọ̀. Kín ní àwọn ohun ọ̀tun náà tó lè mù ẹ̀yín òǹkàwé rí nǹkan túntún nínú ẹ̀dà yìí? Bóko kò jìnnà, ilá kì í kó.

Ìgbà àkọ́kọ́ nìyí tí gbogbo bébà ìnú ìwé àtìgbàdégbà yìí dá lórí lítíréṣọ̀ Áfíríkà nìkan, tí gbogbo bébà náà sì jẹ́ kíkọ ní kìkìdá ojúlówó èdè ilẹ̀ Adúláwọ̀.

Àwọ́n tó nímọ̀ nípa lítíréṣọ̀ alohùn àti èdè Áfíríkà tí wọn sì ti ṣe iṣẹ́ ìwádìí kan gbógì tàbí òmìíràn ló dá bébà jọ láti tan ìmọ́lẹ̀ yẹbẹyẹbẹ sí lítíréṣọ̀ náà, kí òye rẹ̀ lè yé ẹnikẹ́ni. Latí mú èyí rọrùn fún àwọn òǹkàwé àti olùwádìí, olóòtú àgbà, Alexandre Timbane, ṣakitiyan láti rí i pé àwọn bébà inú jọ́nà yìí ní ìtúmọ̀ ní èdè Potokí lérẹ́fèé. Lára awọn èdè tó jẹ òpómúléró nínú ọ̀tọ̀lọ́rìn yìí ni àwọn èdè Akan/Twi, Ga, Hausa, Nzema, Somali, Urhobo, Wolof, àti Yorùbá.

Ohun miiran ni pe àwọn bébà inú jọ́nà yìí pín sí ìsọ̀rí. Awọn bébà tó wà ní èdè Gáà wà lábẹ̀ orúkọ èdè náà. Bẹ́ẹ̀ ní ti àwọn èdè kan yòókù náà sì rí. Láríjà èyí ni láti mú ìwé kíkà rọrùn fún àwọn òǹkàwé. Èdè àwújọ adúláwọ̀ tó jẹ àwọn òǹkọ̀wé lógún tí wọ́n lò ń lọ bíi èdè mẹ́sàn-án.

Yàtọ̀ sí pé àwọn ónímọ̀ ló kọ àwọn bébà inú jọ́nà yìí, àwọn láméyìítọ̀ tó gbédè, tí wọn sì tún mọ nípa lítíréṣọ̀ àti Ilẹ̀ Adúláwọ̀ ló yẹ awọn bébà náà wò kó tó fojú bòde.

Bí a bá rẹ́kọ, tá rí ọ̀lẹ̀lẹ̀, ká pàlàwẹ̀ wọn ló kú, kọ́wọ́ ó má ṣàfara, kọ́fun ó lè tètè mọ adùn tó ń wọ káà ẹnu. Kí á má déènà pẹnu; ká síṣọ l'órí eégùn.

Oríṣìírísìí bébà Yorùbá ló wà nínú àkànṣe jọ́nà yìí. Àwọn átíkù tó fi ìṣẹ́ ìwádìí hàn ló pé sínú rẹ. Lára àwọn bébà náà ni a ti rí ìṣẹ́ Ọlálérè Adéyẹmi, nínú èyí tó ti ṣe ìtúpalẹ̀ ewì alohùn nínú ìwé èré onítàn Ọmọ Alátẹ Ìlẹ̀kẹ̀ tí Láwuyì Ògúndìran kọ. Iṣẹ́ yìí jẹ́ kí òǹkáwé mọ̀ pé omi-ara ni ewì alohùn jẹ́ fún lítíréṣọ̀ alákọsílẹ̀ yìí. Bébà mìíràn ni ti Luqman Abíṣọ́lá Kílaríbẹ̀ẹ́ àti Phillip Adédọ̀tún Ògúndèjì tó dá lé orí ijó àti orin kete àti orin agbè. Bébà yìí ṣe àpèjúwe àwọn ijó ní ìbámu pẹ̀lú orin kíkọ. Ó sì kún fún àwòrán àwọn oníjó. Àwọn àwòrán náà tóbi dáadáa fún òǹkàwé láti rí kedegbe àti láti gbọ́ àgbọ́yé nípa nǹkan tí àwọn àwòrán náà ń sọ.

Àwọn bébà lèdè Yorùbá kò pín sórí ìwádìí nípa ijó; ó tún ní àwọn ìpín mìíràn tí wọn wo abala lítíréṣọ̀ alohùn. Fún àpẹẹrẹ, nígbà tí Ọmọlayọ̀ Ògúnlọla lo bébà rẹ láti tan ìmọ́lẹ̀ sí ojúṣe àwọn èrò ìwòran nínú lítíréṣọ̀ Yorùbá, Adéọlá Adijat Fálẹ́yẹ lo bébà tirẹ̀ láti ṣe ìtúpalẹ̀ "èrò ìjìnlẹ̀ nípa agbára Olódùmarè lóri ìsọ̀rí ìṣẹ̀dá abẹ̀mí àti ajẹmẹ́ranko nínú ìlò oríkì. Bẹ́ẹ̀ ni bébà Raphael A. Adésuyan tẹjú mọ ọ̀nà-èdè alátinúdá ajẹmẹ́wà inú òwe. Iṣẹ́ ti Adéwálé Lukuman Adémúyíwá wo ọgbọ́n ìṣẹ̀dá afọ̀ láti tóka ìlànà láti ṣe ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ alohùn.

Kò tán síbẹ̀, àwọn bébà mìíràn tún wà tó tú iṣu lítíréṣọ̀ alohùn tó jẹ mọ obìnrin àti òrìṣà jáde dáadáa. Fún àpẹẹrẹ, bébà ti Àrìnpé G. Adéjùmọ̀ sípayá "lórí onírúurú ọ̀nà ìjóbìnrin nínú àṣàyán ọ̀nà aláwòmọ́ lííítíréṣọ Yorùbá" nígbà tí bébà ti Abídèmí Bọ́láríǹwá ṣe àfihàn àwọn obìnrin nínú orin àlọ́ onítàn Yorùbá.

Bẹ́ẹ̀ ní àwọn bébà mìíràn wà nínú jọ́nà yìí tí wọn jẹ mọ́ àwọn òrìṣà àti agbára Olódùmarè. Àpẹẹrẹ ni bébà Fáwọlé Ìlúfóyè Òjó tó sọ nípa ìwúlò eré àti ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ̀ fún àtúnṣe làwùjọ ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà, bébà Taofiq Sa'adu ṣe ìtúpalẹ̀ ewì tó jẹ mọ́ Èṣù láti fi agbára òrìṣà náà hàn nígbà tí bébà tí J. Gbénga Fágbọrún sì dá lé orí "ètò ìṣirò áládádé méjì àti odù-Ifá," léyìí tó jẹ mọ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ kọ̀ḿpútà lóde-òní. Fúnmiláyọ̀ Tèmítọ́pẹ́ Àjàyí náà ṣe àgbéyẹ̀wó òhun tí Ifá sọ nípa àwọn ẹranko kan láti fi ibájọ àti ìyàtọ̀ àwọn ẹ̀dá méjèjì hàn. Béba ti Adéọlá Adijat Fálẹ́yẹ ṣe ìtúpalẹ̀ sí oríkì tí ó jẹ ògbóntarìgì èèkàn tàbí oríṣìí lítíréṣọ̀ Yorùbá kan láti férò ìjìnlẹ̀ àwọn ọmọ Kú-oótù-o-ò-jíire hàn "nípa agbára Olódùmarè, ìṣọ̀rí ìṣẹ̀dá abẹ̀mí, àti ajẹmẹ́ranko."

Bébá méjì mìíràn ni ti Táíwò Ọpẹ́yẹmí Akíndutí tó tan ìmọ́lẹ̀ sí ìdí tàbí ìwúlò ọdún Ọpa ní Ìlú Osí àti Ìlú Ìpínṣà ati èyí tí Hakeem Ọláwálé kọ nípa "orin dadakúàdà gẹ́gẹ́ bí atọ́nà ìgbáyégbádùn láwújọ."

Bákan náà ni bébà mìíràn tí Luqman Abíṣọ́lá Kílaríbẹ̀ẹ́ kọ tẹjú mọ̀ ọ̀nà ìgbékalẹ̀ àti ìpèdè tàbí orin agbè tó ṣe àfihàn ìperà-ẹni-níjà láàrin àwọn òṣèré orin náà. Bébà yìí ní àwọn àwòrán tó ṣègbè fún ìgbékalẹ̀ awọn kókó tí òǹkọ̀wé náà yíká sí, tó sì mú ní ọ̀kúnkúndùn nínú àlàyé àti àpèjúwe to ṣe. Àwòrán kòǹgbà tó níí ṣe pẹ̀lú eré náà, tó sì ní ìtumọ̀ sí èèyàn tó bá rí wọn lè jẹ́ òǹfà fún àwọn tó bá sí ojú-ìwé jọ́nà yìí wò.

Kò sí ibi tí a kì í ti í dáná alẹ́, ọbẹ̀ nìkàn níí dùn jura wọn lọ. Gbogbo àwọn bébà lédè yòókù kò ṣe é fọwọ́ rọ́ ṣẹ́yìn. Fún àpẹẹrẹ, Bébà tí Yakub Mohammed ati John Nyame jọ kọ nípa ọ̀nà-èdè tó jẹ mọ́ ojú. Bébà yìí ṣe àgbéyẹ̀wò bí àwọn ìran Nzema ní orílẹ̀-èdè Ghana tí ń ṣe àgbékalẹ̀ ọ̀rọ̀ wọn lọ́nà tó rẹwà, tó ṣe é gbọ́, tó níí ṣe pẹ̀lú ojú, ẹ̀yà ara tó jẹ́ kò-ṣe-é-má-ní. Ìwádìí bí irú èyí kò wọ́pọ̀ nípa ìlò ọ̀nà-èdè náà. Èyí mú kí bébà náà kó ipa pàtàkì nínú jọ́nà yìí, gẹ́gẹ́ bí àwọn òǹkọ́wé náà ti sọ. Àwọn Yorùbá bọ̀; wọ́n ní ojú kúkú ni baba ara; ẹsẹ̀ sì ni baba ìrín. Nínú bébà  mìíràn tí àwọn méjèèjì tún jọ kọ, wọn ṣe àgbéyẹ̀wò ohùn tàbí ewì arò láàrin àwọn ẹ̀yà náà. Bébà yìí sọ nípa ìdárò abẹ̀mí. Báde Àjùwọ́n sọ nínú ìwé Yorùbá tó kọ, tó pé ní *Ìrèmọ̀jé: Eré Ìṣípà Ọdẹ*, pé ipa tí àwon èèyàn kó kí wọn tó fayé sílẹ̀ ni àwọn ará ayé ń rántí tí wọn bá ń sun ìrèmọ̀jé láti dárò níbi òkú àgbà ọdẹ. Yàtọ̀ sí bébà àjùmọ̀kọ lédè Nzema, John Nyame dá bébà kan kọ. O ṣe àgbéyẹ̀wò oríṣìíríṣìí orin amúṣẹ́yá láàrin àwọn Nzema. Ó wo ẹ̀hún àti ìwúlò wọn láti tọ́ka àbùdá orin wọn.

Bébà mìíràn ní èyí ti Matilda Nuertekieà Tetteh Donkor kọ ní èdè Gáà. Ó dá lé orí orin àwọn ẹ̀ka àwọn Kpone tó jẹ ara àwọn ẹ̀yà Gaa ni Ghana. Orin ayẹyẹ tí ó wà lórí fọ́nrán ló ṣe ìwádìí nípa rẹ̀. Ó fa ẹ̀rí jáde nínú orin mẹ́rìnlá tí Tetteh ṣe àgbéyẹ̀wò wọn láti fi hàn pé ọ̀rọ̀ ọmọlúàbí, ìmọ̀ràn áwújọ gbígbà, àti ìtọjú ohun ìṣẹ̀ǹbáyé jẹ àwọn Gáà lógún.

Ẹ̀yà Gaa ní Ghana jẹ́ ọmọ Yorùbá tó tí kúrò ní Ilé-Ifẹ̀ tó orírun àwọn Yorùbá ní Nàìjíríà láti ọjọ́ pípẹ́. Bóyá ìdí nìyí tí kòkó ìn nú bébà Tetteh kò fí yàtọ̀ sí ohun tó jẹ àwọn Yorùbá lógún. Ọmọ àjànàkú kìí kúkú ya ìrá; ọmọ tẹ́kùn bá bí, ẹkùn ní yóò jọ.

Bébà méjì lédè Hausa ló wà nínú jọ́nà yìí. Wọ́n dá lé orí orin ìbílẹ̀. Nínú bébà ti Isa Umar A-Musawi, ó lo tíọ́rì abójúayému láti ṣe ìtúpalẹ̀ orin "Mai Akwai da Babu" tí Alhaji Dr. Adamu Danmaraya Jos kọ. Ò sì gúnlẹ̀ sórí pé ìkú lópin ẹni gbogbo. Ní ti Abu-Ubaida Sani, o wo ipa tí àwọn orin ìbílẹ̀ tó wà nínú fọ́nrán ń kó nínú ìgbésí-ayé àwọn to the Hausa.

Raymond Amoakwa lo èdè Akan láti kọ bébà lórí ìbáṣepọ̀ lítíréṣọ̀ alohùn àti oríṣìíríṣìí nǹkan àwùjọ bíi aṣọ híhun, òwe pípa, ìtàn sísọ, ìṣe, ìtàn, òwe, ọ̀rọ̀ nípa ìwá ọmọlúàbí, àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ sará aṣọ láti fá ọ̀gbọ́n àti òye jáde gẹ́gẹ́ bí ìṣe àwọn ẹ̀yà Akan/Twi. Àwórán gbẹ̀gẹ̀dẹ̀gbẹ̀gẹ̀dẹ̀ àti ìtọ́kasí tí kìí jẹ kéèyàn pàdánù nǹkan iṣẹ́nbáyé wọn ló wà nínú bébà yìí. Bébà yìí wúlò fẹ́nikẹ́ni tó bá fẹ́ mọ nípa ọ̀pọ̀lọpọ̀ nǹkan àwùjọ náà.

Bí jọ́nà yìí tí ní bébà alákadá lóríṣìí, bẹ́ẹ̀ náà ló ní èwí nínú. Fún àpẹẹrẹ, ewì tí àkọlé rẹ̀ ń je "Nnianim" kún fún àtinúdà Patience Òbeng tó fi ìmọ̀ rẹ nípa èdè àtì ewì alohùn Akan/Twi ṣe òté láti fi gbé ewì rẹ̀ tó sọ onírúurú ìrírí kàlẹ̀ lọ́nà tó dùn tó sì ní ìtúmọ̀ láwùjọ awọn ẹ̀yà tó lo àṣà wọn.

Kìí ṣe ewì Akan/Twi nìkan ni jọ́nà yìí gbé jáde ní sáà yìí. Ewì èdè Wolof, Somali àti Yorùbá náà wà nínú jọ́nà yìí. Mariam Sy lo ewì rẹ̀ tó kọ ní èdè Wolof láti fi pe àwùjọ níjà nípa ìrírí rẹ̀ léyìí tó dúró fún ìrírí àwọn obìnrin. Bébà mìíràn ni ti Maryan Ali to sọ ìtán arosọ lédè Somali láti kọ́ awọn òǹkàwé lọ́mọdé lọ́gbọ́n bí ènìyàn ṣe lè gbé ilé ayé nípo tó bá wà. Èwí mìíràn ni èyí tí Báyọ̀ Ọmọlọ́lá kọ tó pe àwọn olóṣèlú àti ará ìlú níjà nípa bí nǹkan tí ń dagun lójú wọn.

Kò ì tán; àwọn bébà èdè Urhobo náà wà. Ìgbà àkọ́kọ́ lèyí máa jẹ tí àwọn tó n ka jọ́nà yìí yóò kà dáadáa nípa ọ̀gbọ́n ìkọ́ní ní lítíréṣọ̀ alohùn. Eyankuaire Moses Darah àti Godwin Avweosuo Ivworin lo bébà wọn láti sípáyá àwọn ohùn ìlò ohùn lóríṣìíṣìí àti ipa wọn nínú lítíréṣọ̀ àwọn Urhobo Urhobo ní Ìpínlẹ̀ Delta, Nàìjíríà. Bébà mìíràn ní ti Lucky Oghenerume Ejobee tó wo ògbọ́n ìlò-èdè àti òwe láti bù ẹwà kún iṣẹ́ lítíréṣọ̀ alohùn àwọn Urhobo. Bébà kẹta ni èyí tí Oghenerume Lucky Ejobee àti Benjamin Akpovona Iverarekọ kọ lórí dídákẹ́ nínú lítíréṣọ̀ alohùn Urhobo. Bébà wọn wo àlébù àti ìwúlò ki onísẹ́ lítíréṣọ̀ alohùn dédé dákẹ́. Nípa ìlànà ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò, àwọn tó kọ bébà yìí rí nǹkan sàjọ láti gùnmọ́ sọ ohun tí wọn fà yọ nínú ìwádìí wọn.

Àwọn bébà inú ẹ̀dá *Njinga & Sepé* ọ̀tọ̀lórìn yìí dà bí àgbá tó ní omi funfun tó mọ́ geere fẹnikẹ́ni tí òǹgbẹ ń gbẹ tábí tí wọn kàn ń wá àwákún ìmọ̀ nípa nípa lítíréṣọ̀ alohùn ìlẹ̀ Áfíríkà. Ojúọ̀álápé ní jọ́nà àkànṣe yìí. Ó kún fún àwọn bèbà tó níí ṣe àṣà, ìṣe, ijó, orin, òrìṣà, ilẹ̀ Adúláwọ̀, ìkọ́ṣẹ́ lítíréṣọ̀, ewì, ìtàn, àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ.

Ìtọ́wó ni fáárá yìí. Bí ìgbà ti èèyàn gbóòórún ọbẹ̀ tó ta sánsán lásán ni yóò jẹ́ bí èèyàn kò bá ta sàsà ká àwọn bébà inú jọ́nà yii. Èwo ló tún kú? Ìyókú dọwọ́ ẹ̀yin òǹkàwé! Ẹ má ṣàfara.

Bayọ Ọmọlọ́lá

Olóòtú

Olóòtú, Àkànṣe Lórí Lítíréṣọ̀ Alohùn Áfíríkà

**Bayọ Ọmọlọla, Ph.D**



Instructor/Lecturer, Editor, *Zambezia*, *Journal of Humanities* at University of Zimbabwe, Advisor, *Omoran: Journal Ede Yoruba, Editor Guest*, Special Issue on African Verbal Arts, *Njinga & Sepé* Recipient of Meritorious and Service Award 2025, Given by the American Association of Yoruba Teachers (AATY), College of Liberal Arts, Department of World Languages and International Studies, Holmes Room 311, Department of English and Language Arts. Morgan State University. E-mail: Bayo.Omolola@morgan.edu



**Para citar este texto (ABNT):** ỌMỌLỌLA, Bayọ. Ìfáárà: *Njinga & Sepé* Gbé Àkànṣe Yìí Jáde Lórí Lítíréṣọ̀ Alohùn Ìlẹ̀ Adúláwọ̀. *Njinga & Sepé:* Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras. São Francisco do Conde (BA), vol.5, nº Especial I, p. 07-10, jan./ jun.2025.

**Para citar este texto (APA):** Ọmọlọla, Bayọ. (jan./ jun.2025). Ìfáárà: *Njinga & Sepé* Gbé Àkànṣe Yìí Jáde Lórí Lítíréṣọ̀ Alohùn Ìlẹ̀ Adúláwọ̀. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), 5 (Especial I): 07-10.

## SUMÁRIO /TABLE OF CONTENTES/ ÀKÓÓNÚ

**Akoonu** **Oju-Iwe**

**Ifihan / igbejade, Guest Editor** ........................................................................ **07-10**

**1.Ewì Alohùn Nínú Lítíréṣọ̀ Àpilẹ̀kọ Yorùbá: Ìwé Eré-onítàn *Ọmọ Aláte Ìlẹ̀kẹ̀* tí Láwuyì Ògúnniran kọ bí Àpẹẹrẹ**

**Ọlálérè ADÉYẸMÍ** ........................................................................ **11-31**

**2.Àgbéyẹ̀wò Oríṣiríṣi Ijó nínú Ìṣeré Orin Kete àti Orin Agbè**

**Luqman Abíṣọ́lá KÍARÍBẸ̀Ẹ́ & Philip Adédọ̀tun ÒGÚNDÈJÌ** ........................ **32-60**

**3.Ojúṣe èrò ìwòran nínú àgbéjádé lítíréṣọ̀ alohùn yorùbá**

**Ọmọlayọ̀ Dúrótadé ÒGÚNLỌLÁ** ........................................................ **61-70**

**4.Òwe Yorùbá Gẹ́gẹ́ bí Àpẹẹrẹ Ọnà-èdè Alátinúdá Ajẹmẹ́wà: Kò Gbọdọ̀ Kú**

**Raphael A. ADESUYAN**........ ................................................................ **71-79**

**5.Àtúpalẹ̀ Ìṣàfihàn Èrò Ìjìnlẹ̀ nípa Agbára Olódùmarè lórí Ìsọ̀rí Ìṣẹ̀dàá Abẹ̀mí, àti Ajẹmẹ́ranko nínú Ìlò Oríkì**

**Adéọlá Adijat FÁLẸ́YE**........................................................................ **80-110**

**6.Ìṣàmúlò Eré àti Ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ fún Àyípadà Àwùjọ àti Àtúnṣe ní Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà**

**Ìlúfóyè Fáwọlé ÒJÓ** ........................................................................ **111-126**

**7.Ìṣàfihàn onírúurú ọ̀nà ìjóbìnrin nínú àṣàyàn iṣẹ́ ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ yorùbá**

**Àrìnpé G. ADÉJÙMỌ̀**........................................................................ **127-139**

**8.Ọgbọ́n ìṣẹ̀dá àti àwòmọ́ afọ̀: ìlànà fún ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ alohùn yorùbá**

Adewale Lukman ADEMUYIWA………….…………………………………………………….. 140-153
9. Àfihàn agbára èṣù nínú àsàyàn ewì ajẹméṣu
Taofiq SA'ADU ………………………………………………………..……………………….. 154-171
10. Ìpera-ẹni-níjà nínú Ìṣeré Orin Agbè
Luqman Abísọ̀lá KÍARÍBẸ̀Ẹ́ ………………..……………………………………………….. 172-187
11.Ìdálùú Nìṣèlú – Láríjà Àkóónú Ọdún Ọ̀pá ní Ìlú Osí àti Ìlú Ìpinṣà
Taiwo Ọpẹyẹmi AKINDUTI ……………..…………………………………………………… 188-201
12.Àfihàn obìnrin nínú àwọn àsàyàn orin àlọ onítàn yorùbá
Abídèmí BỌ́LÁRÌNWÁ………………………………………………………………………… 202-215
13. Orin dàdàkúàdà gẹ́gẹ́ bí atọ́nà ìgbáyégbádùn láwùjọ
Hakeem ỌLÁWÁLÉ ……..……………………………………………………………….. 216-227
14.Ètò ìṣirò aládàdé-méjì àti àmúlùmọ́là odù ifá
J. Gbenga FÁGBỌ́RUN ……..………………………………………………………………… 228-234
15.Àfihàn Ohun tí Ifá sọ Nípa Aṣàyàn Ẹranko Láwùjọ Yorùbá
Fúnmiláyọ̀ Tèmítọ́pẹ́ ÀJÀYÍ ……………………………………………………………..…… 235-242
16. Jongoma
Mariame Iyane SY……………………………………………………………………………… 243-248
17. Ta Ló Lè Ṣe É?
Báyọ̀ ỌMỌLỌLÁ ……………………………………………………………………………… 249-251
18.Eriendo rẹ Ọtaphia: Efuẹrẹ rẹ ekuakue rẹ Uhworo vwẹ ona rẹ Ọtaphia
Eyankuaire Moses DARAH & Dr Godwin Avwerosuo IVWORIN ......................... 252-263